# OFIN MẸWA

## Ẹksodu 20:1-17

## ẸKỌ 61 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ máṣe rò pe, emi wa lati pa ofin tabi awọn woli run: emi kò wá lati parun, bikoṣe lati muṣẹ" (Matteu 5:17).**

**I "Iwọ kò gbọdọ li ọlọrun miran pẹlu mi"**

**II "Iwọ kò gbọdọ yá ère fun ara rẹ, tabi aworan ohun kan ti bẹ loke ọrun, tabi ti ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ, tabi ti ohun kan ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ; Iwọ kò gbọdọ tẹ ori ara rẹ ba fun wọn, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitori emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, Ọlọrun owu ni mi, ti mbẹ ẹ̀ṣẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, lati irandiran kẹta ati ẹkẹrin ninu awọn ti o korira mi; Emi a si ma fi anu hàn ẹgbẹgbẹrun awọn ti o fẹ mi, ti nwọn si npa ofin mi mọ́."**

**III "Iwọ kò gbọdọ pe orukọ OLUWA Ọlọrun rẹ lasan; nitoriti OLUWA ki yio mu awọn ti o pe orukọ rẹ lasan bi alailẹṣẹ li ọrùn."**

**IV "Ranti ọjọ isimi lati yà a si mimọ́, Ọjọ mẹfa ni iwọ o ṣiṣẹ, ti iwọ o si ṣe iṣẹ rẹ gbogbo: Ṣugbọn ọjọ́ keje li ọjọ isimi OLUWA Ọlọrun rẹ: ninu rẹ̀ iwọ kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan, iwọ ati ọmọ rẹ ọkunrin, ati ọmọ rẹ obirin, ọmọ-ọdọ rẹ ọkunrin, ati ọmọ-ọdọ rẹ obinrin, ohun-osin rẹ ati àlejò rẹ ti mbẹ ninu ibode ẹ: Nitori ni ijọ mẹfa li OLUWA dá orun on aiye, okun ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu wọn, o si simi ni ijọ keje: nitorina li OLUWA ṣe busi ijọ keje, o si ya a si mimọ́."**

**V "Bọwọ fun baba on iya rẹ ki ọjọ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ."**

**VI "Iwọ kò gbọdọ pania"**

**VII "Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga."**

**VIII "Iwọ kò gbọdọ jale"**

**IX "Iwọ kò gbọdọ jẹri eke si ẹnikeji rẹ.**

**X "Iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si ile ẹnikeji rẹ, iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro si aya ẹnikeji rẹ, tabi si ọmọ-ọdọ rẹ ọkunrin, tabi ọmọ-ọdọ obirin, akọ-malu rẹ, kẹtẹkẹtẹ rẹ, tabi ohun gbogbo ti I ṣe ti ẹnikeji rẹ."**

## ALAYE

Ọrọ Ọlọrun ti a to lẹsẹẹsẹ ni awọn ofin ti n ṣakoso ibalo wọn pẹlu ara wọn ati ilana isin.

Ẹksodu 20:3-17 ni a pin si ọna pupọ ti a n pe ni **Ofin Mẹwa**. "OLUWA si sọ̀rọ si nyin lati ãrin iná na wá: ẹnyin gbọ́ ohun ọrọ na, ṣugbọn ẹ kò ri apẹrẹ kan; kiki ohùn li ẹnyin gbọ́. O si sọ majẹmu rẹ̀ fun nyin, ti o palaṣẹ fun nyin lati ṣe, ani **ofin mẹwa** nì; o si kọ ọn sara walã okuta meji" (Deuteronomi 4:12, 13).

### Ofin ti a ti Ọwọ Ọlọrun Kọ

Bi o tilẹ jẹ pe "gbogbo iwe mimọ li o ni imisi Ọlọrun," sibẹ, ọkan ni yi ti Ọlọrun tikara Rẹ̀ kọ: "O si fi wala ẹri méji, wala okuta, ti a fi ika Ọlọrun kọ fun Mose, nigbati o pari ọ̀rọ bibá a sọ tán lori oke Sinai" (Ẹksodu 31:18). Ofin Mẹwa ṣe iyebiye to bẹẹ gẹẹ ti a fi fi fun ni pẹlu mànamána, aara, iro ipe, ati eefin ati iná, eyi ti o mu Mose ati awọn Ọmọ Israẹli wariri gẹgẹ bi a ti kà ninu ẹkọ wa sẹhin. **Ofin Mẹwa** wọnyi si ni M**ajẹmu** ti Israẹli fi tọwọtọwọ ba Ọlọrun da, nigba ti wọn wi pe, "Ohun gbogbo ti OLUWA wi li awa o ṣe" (Ẹksodu 19:8). Awọn ọ̀rọ wọnyi ni o ṣiwaju Ofin Mẹwa naa: "Ọlọrun si sọ gbogbo ọ̀rọ wọnyi pe, Emi li OLUWA Ọlọrun rẹ ti o mu ọ jade lati ilẹ Egipti, lati oko-ẹrú jade wá." Gẹgẹ bi a ti kà, idasilẹ Israẹli kuro ni Egipti jẹ apẹẹrẹ iriri idalare. Nitori naa, ọrọ iṣaaju yi ni pe pipa aṣẹ Ọlorun mọ́ jẹ Majẹmu ti eniyan ba Ọlorun dá nigba ti a ba da a lare. "Ibukun ni fun ọkunrin na ti kò rin ni imọ̀ awọn enia buburu, ti kò duro li ọ̀na awọn ẹlẹṣẹ, ati ti kò si joko ni ibujoko awọn ẹlẹgan. Ṣugbọn didun-inu rẹ̀ wà ni ofin OLUWA; ati ninu ofin rẹ li o nṣe aṣaro li ọsan ati li oru" (Orin Dafidi 1:1, 2).

### Aṣẹ Wọnyi ni Olu Ofin

Ofin Mẹwa wọnyi – tabi Ofin Ọlọrun -- pọ ju apa kan Ofin ti Ọlorun ti ipasẹ Mose fi fun ni lori Oke Sinai. Ofin Mẹwa ni olu ofin tikara rẹ; awọn si ni pataki ti a pin si oniruuru ọna ti a to lẹsẹẹsẹ ti a si ṣe alaye rẹ ninu awọn iwe Mose eyi ti awọn woli fi kọ ni.

Gbogbo igbesi-aye eniyan Ọlọrun lojoojumọ ni a tumọ sinu Ọrọ Ọlọrun ninu Ofin Mẹwa, "ati ni pipamọ wọn, ere pipọ mbẹ." Pa awọn Ofin Mẹwa wọnyi mọ́, iwọ o si maa "gbe ni alafia, ni ododo ati ni iwa-bi-Ọlọrun laiye isisiyi." Ohun iyanu wo ni eyi pe iba awọn ọrọ kekere wọnyi ti o ye ni ti o si rọrun lati ba ẹri ọkan ọlukuluku eniyan sọrọ, ni akópọ ati koko ọ̀rọ gbogbo Ofin Ọlọrun. Dajudaju, nitori idi eyi ni a ṣe tete kọ́ fun ni ni Ofin Mẹwa lori Oke Sinai, ṣiwaju awọn ofin miran.

Ki i ṣe awọn Ọmọ Israẹli nikan ni Ọlọrun fun ni Ofin wọnyi, bi ko ṣe fun gbogbo agbaye. Oun kò fi fun wọn lati gbadun rẹ lasan bi ẹkọ giga kan ṣa, ṣugbọn gẹgẹ bi ofin akoso igbesi-aye ti gbogbo eniyan ni lati tẹle. A si ṣe alaye eyi yekeyeke ninu Majẹmu Laelae ati Majẹmu Titun. "Mimọ́ li ofin, mimọ́ si li aṣẹ, ati ododo, ati didara" (Romu 7:12). Ẹni ti o ba si jẹbi rirú Ofin o jẹbi ere rẹ ti i ṣe ijiya ainipẹkun ti o daju, "nitori ẹ̀ṣẹ ni riru ofin" (I Johannu 3:4). A si tun kà ninu awọn iwe Paulu pe, "Nitori iye awọn ti o ṣẹ̀ li ailofin, nwọn si ṣegbé lailofin: ati iye awọn ti o ṣẹ labẹ ofin, awọn li a o fi ofin dalẹjọ" (Romu 2:12).

## A Fi Idajọ ati Aanu Ọlọrun Hàn ninu Ofin

Bayi ni Ofin mimọ́ Ọlọrun fi idajọ Rẹ̀ hàn, eyi ti o fara han ninu manamana, aara, iró ipe ati eefin ati ina ni Sinai niwaju eyi ti Israẹli wariri. Ṣugbọn a ko ni dẹkun lati maa yin Orukọ Rẹ̀ pe Ọlọrun alaanu ni Oun i ṣe pẹlu. Nitori idi eyi, ọna ati là wa fun ẹni ti o jẹbi rirú Ofin Rẹ̀. Olukuluku ọmọ Adamu, lati igbà ẹṣẹ akọkọ ni Ọgba Edẹni, ni o jẹbi riru Ofin Ọlọrun. "Nitori gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀ ti wọn si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3:23). Nitori naa, nigba ti Ọlọrun mu awọn Ọmọ Israẹli jade ni Egipti, O pese ọdọ-agutan irekọja fun wọn, eyi ti wọn fi ẹjẹ rẹ wọn atẹrigba ati òpo ile wọn; Ọlọrun si wi pe, "Nigbati emi ba ri ẹ̀jẹ̀ na emi o re nyin kọja." Johannu Baptisti fi titobi tumọ́ ọdọ-agutan irekọja naa han loke odo Jọrdani, bi oun ti tọka si Ẹni kan ṣoṣo naa ti n bọ wá sọdọ rẹ, o kigbe wi pe, "Wò o Ọdọ-Agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!" (Johannu 1:29). Bayi ni gbogbo ẹbọ ti a n ṣe ninu isin agọ ni aginju tọka si Ọmọ Ọlọrun Ẹni ti "O de lati wá awọn ti o nu kiri ati lati gba wọn là." "Nitori ohun ti ofin kò le ṣe, bi o ti jẹ alailera nitori ara, Ọlorun rán Ọmọ oun tikara rẹ̀ li aworan ara ẹ̀ṣẹ, ati bi ẹbọ fun ẹṣẹ, o si da ẹṣẹ lẹbi ninu ara. Ki a le mú ododo ofin ṣẹ ninu awa ti ko rin nipa ti ara, bikoṣe nipa ti Ẹmi" (Romu 8:3, 4).

Bayi ni o fara han gbangba pe Ọlọrun mu awọn Ọmọ Israẹli lọ si Oke Sinai fun idi pataki pe ki Oun ba le fun wọn ni Ofin Rẹ̀ ati ki wọn ba le maa rin ninu rẹ. Eyi ni wọn si gba lati ṣe nigba ti wọn wi pe, "Ohun gbogbo ti OLUWA wi li awa o ṣe." Ṣugbọn "gbogbo awọn enia na si ri ãra na, ati manamana na ati ohùn ipe na, nwọn ri oke na nṣe ẽfi: nigbati awọn enia si ri i, nwọn ṣí, nwọn si duro li òkere réré. Nwọn si wi fun Mose pe, Iwọ ma bá wa sọrọ, awa o si gbọ́: ṣugbọn máṣe jẹ ki Ọlọrun ki o ba wa sọrọ, ki awa ki o má bã kú" (Ẹksodu 20:18, 19). Bayi ni awọn Ọmọ Israẹli fa sẹhin kuro lọdọ Ọlọrun, wọn si kùna ipe giga Ọlọrun patapata. Wọn ru ofin Rẹ̀, wọn si ba majẹmu wọn pẹlu Ọlọrun jẹ, OLUWA si kọ wọn silẹ nikẹhin. "Ṣugbọn olododo ni yio yè nipa igbagbọ́: ṣugbọn bi o bá fa sẹhin, ọkan mi kò ni inu-didun siiI" (Heberu 10:38).

## Ofin ti a Kọ sinu Ọkan

Ni igba aye Jeremiah, ti awọn Ọmọ Isaẹli pada sẹhin tan patapata, OLUWA ti ẹnu woli naa sọ bayi pe, "Wo o, ọjọ mbọ li OLUWA wi, ti emi o ba ile Israẹli ati ile Judah da majẹmu titun. Ki i ṣe bi majẹmu na ti emi ba baba wọn dá li ọjọ na ti emi fa wọn lọwọ lati mú wọn jade lati ilẹ Egipti: awọn ti nwọn da majẹmu mi, … ṣugbọn eyi ni majẹmu ti emi o ba ile Israẹli da; lẹhin ọjọ wọnni, li OLUWA wi, emi o fi ofin mi si inu wọn, emi o si kọ ọ si aiya wọn, emi o si jẹ Ọlọrun wọn, awọn o si jẹ enia mi" (Jeremiah 31:31-33). Paulu Apọsteli, ninu Episteli rẹ si awon Heberu, sọ awọn ọrọ kan naa (Heberu 8:8-10), o si tumọ Majẹmu Titun yi si Ihinrere ti a ti ipasẹ Jesu Kristi mú wa sinu aye, lakoko eyi ti a mú Majẹmu Laelae kuro, eyi ti a ṣe lori Oke Sinai (Heberu 8:13). Siwaju si i Apọsteli naa ṣe alaye pe a maa n kọ Ofin Ọlọrun si ọkan nigba ti a ba ni ìrírí isọdimimọ́ patapata: "Nigbana ni o (Jesu Kristi) wi pe, kiyesi i, Mo de lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun. O mú ti iṣãju kuro (majẹmu), ki o le fi idi (majẹmu) ekeji mulẹ. Nipa ifẹ na li a ti sọ wa di mimọ nipa ẹbọ ti Jesu Kristi fi ara rẹ̀ rú lẹkanṣoṣo" (Heberu 10:9, 10). "Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹjẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin bode" (Heberu 13:12). Gẹgẹ bi a si ti tumọ rẹ ninu ẹkọ iṣaaju, a fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu Ofin Rẹ̀. Nitori naa nigba ti a bá sọ ẹni kan di mimọ́ patapata, ẹṣẹ abinibi ni a o parun (Romu 6:6), a o si kọ ofin Ọlọrun sinu ọkan naa. Yoo si rọrun pupọ nigba naa, lati pa ofin Rẹ̀ mọ́.

Nigba ti Ọlọrun mu awọn Ọmọ Israẹli wá si Oke Sinai, Oun i ba sọ wọn di mimọ́ patapata, ki O si kọ Ofin Rẹ̀ si wọn lọkan, ṣugbọn wọn fa sẹhin, wọn si kuna ipe giga Rẹ̀. Ṣugbọn nisinsinyi awa n bẹ labẹ Majẹmu Titun nigba ti a kò kọ Ofin sara wala okuta mọ́, bi ko ṣe ninu ọkan. "Nitorina mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀ nyin, ara, ki ẹnyin ki o fi ara nyin fun Ọlọrun li ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà, eyi ni iṣẹ-isin nyin ti o tọna. Ki ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ aiye yi; ṣugbọn ki ẹ parada lati di titun ni iro-inu nyin, ki ẹnyin ki o le ri idi ifẹ Ọlọrun ti o daa, ti o si ṣe itẹwọgbà, ti o si pé" (Romu 12:1, 2).

## AWỌN IBEERE

1. Kin ni apa kinni Ofin ti a fi fun ni ni Sinai?
2. Kin ni Ofin Mẹwa ti jẹ si awọn Ofin miran?
3. Kin ni ipa mẹta pataki ti a le da awọn ofin Majẹmu Laelae si, lati fi iyatọ hàn si ara wọn?
4. Ewo ninu awọn ipa mẹta pataki wọnyi ti a fi Ofin Mẹwa si?
5. Bawo ni awọn ofin mẹrin iṣaaju ti ṣe yatọ si awọn mẹfa ti o kẹhin?
6. Ofin nla eji wo ni Jesu fi fun ni, lori eyi ti O wi pe "gbogbo ofin ati awọn woli rọ̀ mọ́?"
7. Kin ni ṣe ti awọn Ọmọ Israẹli kuna lati pa Ofin Ọlọrun mọ́?
8. Kin ni ipese ti Ọlọrun ṣe fun pipa Ofin Rẹ̀ mọ́?
9. Kin ni ipese naa jẹ ni igba Majẹmu Laelae?
10. Kin ni ipese naa ni igba Majẹmu Titun?